IBO IB DIPLOMA PROGRAMME
PROGRAMME DU DIPLÔME DU BI
PROGRAMA DEL DIPLOMA DEL BI

M03/157/S(1)

**YORUBA A1 – STANDARD LEVEL – PAPER 1**
**YORUBA A1 – NIVEAU MOYEN – ÉPREUVE 1**
**YORUBA A1 – NIVEL MEDIO – PRUEBA 1**

Monday 19 May 2003 (morning)
Lundi 19 mai 2003 (matin)
Lunes 19 de mayo de 2003 (mañana)

1 hour 30 minutes / 1 heure 30 minutes / 1 hora 30 minutos

---

INSTRUCTIONS TO CANDIDATES

- Do not open this examination paper until instructed to do so.
- Write a commentary on one passage only. It is not compulsory for you to respond directly to the guiding questions provided. However, you may use them if you wish.

INSTRUCTIONS DESTINÉES AUX CANDIDATS

- Ne pas ouvrir cette épreuve avant d'y être autorisé.
- Rédiger un commentaire sur un seul des passages. Le commentaire ne doit pas nécessairement répondre aux questions d'orientation fournies. Vous pouvez toutefois les utiliser si vous le désirez.

INSTRUCCIONES PARA LOS ALUMNOS

- No abra esta prueba hasta que se lo autoricen.
- Escriba un comentario sobre un solo fragmento. No es obligatorio responder directamente a las preguntas que se ofrecen a modo de guía. Sin embargo, puede usarlas si lo desea.

*Kọ àgbóyéè rẹ lórí ọ̀kan nínú àwọn àyọkà méjì wọ̀nyí*

*1. (a)*

**14 Aìdọ̀gba**

Igí gbun n'ígbó a ńsọ ọ!
Ọ̀tọ̀tọ̀ ènìà I'ó gbun lârin ìlú
Nwọ́n ni 'Ará-òrun
Kò pín ọmọ rere.'

Taní ha tó súnmọ́' bẹ̀ ?
Ọ̀ṣùpá léa ní kò lé' re!
Wón l'ẹ́ni ọwọ́ rẹ̀ bá tó o
K'ó lọ tún ṣe!

Èyí t'ó l'ógbe
Kò n'írére!
Èyí t'ó n'írère,
Kò l'ọ́gàn l'ẹ́sẹ̀
Éyí t'ó l'ógàn l'ẹ́sẹ̀
Kò le kọ bí àkùkọ!

Ẹni t'ó l'ẹwà kò l'ẹ́ẹ́wǎ
Ẹni t'ó l'ẹ́ẹ́wǎ kò l'ẹ́wà!
Ẹni t'ó l'éjìká kò l'ẹ́wù
Ẹni t'ó l'ẹ́wù kò l'éjìká

Ẹni t'ó l'éhín kò r'ẹ́ran jẹ,
Ẹni t'ó l'ẹ́ran kò l' éhín !
Ẹni t'ó mọ' Fá kò m'ọ̀nà Ọ̀fà,

Denrele A. Obasa Awon Akewi Apa Kinni OUP Ibadan 1971

– Fa kókó ọ̀rọ̀ inú orin yǐ yọ kí o sì ṣe àlàyée rẹ̀

– Bawo ni akọrin yǐ ṣe lo àwọn gbólóùn láti jẹ́ kí á gbọ́ orin yǐ ye ?

– Ọ̀nà wo ni àgbékalẹ̀ ọ̀rọ̀ nínú orin yǐ ṣe jẹ kí àgbọ́yé rẹ kűn sî ?

– Írú èrò wo tàbí ẹ̀dùn ọkàn wo ni orin yǐ mú jáde lọ́kàn rẹ ?

## Apá Karŭn

1. (b)

# *Mo lu Olódodo ní jìbìtì*

Ọmọ ọdun mẹtalelogun ni mi nigba ti mo sá lọ si Ibadan. Nigba ti mo de Ibadan, mo tun bẹrẹ sií sun abẹ gọta kiri. Mo sọ ara mi di aláàárù lẹẹkan sii nitori ng kò fẹ wa ọkọ̀ mọ, ki a ma baa tete mu mi. Mo tilẹ ti sọ iwe-aṣẹ ti mo fi n wa ọkọ̀ nù láàrin igba ti ìdààmú de ba mi. Ko pẹ ki ng tóó ní ọrẹ ni Ibadan, lẹhin ti mo si sun abẹ gọta fun oṣu kan, ile ọkan ninu awọn ọrẹ mi ni mo tun n sun. Ninu gbogbo awọn ti o n gbe ile rẹ̀ ko si eyi ti o le ri mi l'ode ki o da mi mọ, nitori bi ilẹ̀ ko ṣu daradara emi ki i wa'le, ki o si to di pe a ri ila ọwọ ní owurọ, òjò ń rọ̀, òjò ò rọ̀, ng ó ti jade ní tèmi. Mo fẹ fi iwa ipata silẹ patapata nigba ti mo de Ibadan, nitori ng ko tun fẹ jẹ ọdaran mọ, ṣugbọn ko ṣe i ṣe; ṣugbọn mo gbiyanju ki ng má bọ̀ si awọn ọlọpa lọwọ nitori bi awọn ọlọpa ba tun ri mi mu, oju mi yio kan àtàlátà baba àlàárúba. Nitori èyí ni mo ṣe n mọ iwọn ara mi—bi a ba n sọkun lójú, ṣe à maa ríran, bi aja ba si n sinwin, a máa m'ojú iná.

Owó ti mo n pa lóòjọ́ nibi ààrù kò to nkan bẹẹ ni ounjẹ ti mo n jẹ kò kere. Ṣe ẹyin naa mọ pe ọmọde ti o ba ti n jẹ ètè mààlúù, ẹran kekere ko tun le ká a lẹ́nu mọ́. Ijẹun awọn ọmọ-ijẹka ti mọ́ mi lara. Nigba ti mo kọkọ de Ibadan, bi mo ba ra ọkà tọ́rọ́ ng o ra ẹran ṣile kan; ṣugbọn nigba ti o ya owo ti mo n pa ko to mi í na bẹẹ mọ. Mo gbiyanju ki ng máa jẹun lẹ́ẹ̀mejì lóòjọ́, nitori bi mo ba jẹun lẹ́ẹ̀mejì bi mo ba yo daradara, o pe fun mi ju ki ng máa panu lẹ́ẹ̀mẹta lọ, bẹ́ẹ̀ ni bi mo ba jẹ ẹ̀bà ti ng ko ba jẹ ẹran bi ẹni pe ng kò jẹun rara ni. Mo gbiyanju à ń jẹun lẹrinmeji loojọ fun oṣu kan, ṣugbọn nigba ti ó yá, ng kò rí owó tó lati le jẹun karakara lẹrinmeji loojọ mọ́. Mo gbidanwo ki ng máa jẹun lẹ́ẹ̀kan lóòjọ́ ṣugbọn mo gbé i tì patapata. Nigba ti ọwọ ebi tẹ mi tan patapata mo bẹrẹ sii jẹ ẹ̀bà laisi ẹran. Igba yìí ni mo to mọ pe, bi ẹnikan ba wi pe oun ko le jẹ ijẹkujẹ oluwa rẹ̀ ni owó lọwọ ni. Bi eniyan kò ba ni owó lọwọ bi o ba jẹ ijẹkujẹ tan, yio mu imukumu lé e. Ọbẹ̀ òfifo bẹrẹ sií dun lẹnu mi ju ọbẹ ẹlẹran lọ.

Femi Jeboda <u>Ololayemo</u>, Longman Nigeria Ltd, 1981

– Kí ni olùkọ̀wé yǐ gbìyànjú láti fi yé wa gẹ́gẹ́ bí ó ṣe yé ọ ?

– Sọ ọ̀rọ̀ lórí bí wọ́n ṣe fi ipa tí àwọn ọ̀daràn kó nínú àyokà yǐ hàn.

– Ṣe àlàyé wíwúlò àwon òwe nínú àyọkà yǐ.

– Ọ̀nà wo ni ẹntí ó kọ ìwé yǐ ṣe jẹ́ kí á mọ ìse rẹ̀ lórí oun tí ón sọ̀rọ̀ lé lórí